Ogun Ita'ja

E Polowo oja yin sinu Iwe Irohin Eleti-Ofe, Kia L'oja o ta.

ELETI OFE
A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJO




VOL. X No. 565. ELETI - ỌFẸ LAGOS, SATURDAY, MARCH 29, 1958. KỌBỌ MEJI (2d)

# Adelabu Ku Ilu Ibadan Daru Fun Ojo meji

IBADAN. Rogbodiyan gbojikan kakiri ilu Ibadan lọjọ Alamisi, nigbati awọn gbe oku Adegoke Adelabu de ilu Ibadan, nṣe ni ori gbogbo awọn janduku enia gbona, tobẹ ti nwọn tutọ soke ti nwọn si foju gba jinni-jinni mu gbogbo enia.

Gbogbo awọn ile mọto gobu ipate ti o wa loju opopo ibiti awọn gbe oku na gba ni awọn enia nsọko si, ti nwọn si mbajẹ.

Awọn enia marun ti nwọn yinbọn fun ni nwọn gbe lọ sile alaisan ni Adeoyo. Orukọ awọn enia na niwọnyi:- Lamidi Ajani ti o ngbe Ita Agbakin nwọn yinbọn fun ni ọja Igbo. Garuba Ayinde Oke-Padi awọn yinbọn fun ni ọja Igbo Lasupo Ajagbe ara Alekuṣọ nwọn yinbọn fun ni Alekuṣọ. Ayinde Ajadi ara Alekuṣọ gba ọta ni Ọja Igbo. Sikiru Oyewọ tilẹ ti ku ki nwọn to gbe de.

Nwọn lu awọn elomiran ni kumọ, nwọn sọ okuta lu elomiyan, nwọn ṣa elomiran ni ada, nitori idi eyi, ogunlọgọ awọn ọlọpa ni nwọn da silu ti nwọn si oki awọn enia na mọle.

THE NATIONAL BANK
Of Nigeria Limited

Incorporated in Nigeria in 1938
Paid up Capital – £1,130,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria.
HEAD OFFICE
37, MARINA, LAGOS, NIGERIA

22 Branches throughout Nigeria including
IBADAN ABEOKUTA, IJEBU-ODE,
OSHOGBO, OWO, ONDO ILESHA,
ILARO, BENIN-CITY, WARRI,
SAPELE, ABA, KANO, ZARIA, JOS.

LONDON OFFICE
1 THROGMORTON AVENUE, E.C. 2.
Manager: F. O. Tyrrell

Telephone: London Wall 4303
Cables & Telegrams: Natbaniger, London.
Hon. Office Representative in London.
Ernest Olubunmi Obasa—Porter
CORRESPONDENTS
NEW YORK PARIS HAMBURG

## Isinku Alhaji Adelabu



Enia dabi omi nibi isinku Alhaji Gbadamọsi Adegoke Adelabu nilu Ibadan ni ọjọ Alaruba (Wednesday) ti iṣe ọjọ kẹrindinlọgbọn oṣu March, 1958. Ilu Ibadan ko gba ẹsẹ enia gẹgẹbi enia ti pọ to, ọkunrin ko jẹki a mọ obinrin bẹni ọmọde ko jẹki a mọ agbalagba nibi isinku Alhaji ẹni-mimọ-ti-Ọlọrun na.

Irofọ isinku Alhaji Adelabu ṣ'ọwọn nilu Ibadan, aye ti o fi silẹ larin ẹgbẹ ati ọgba, larin ilu Ibadan yio ṣoro pupọ lati ri enia r'ọpo rẹ.
Adelabu Pẹnkẹlẹmẹsi Ọrun rere.

### AWỌN JANDUKU ENIA NFỌLE

Irohin ti a gbọ nipe awọn janduku enia nfọle kakiri ilu nigbati awọn ngbe oku Alhaji Adelabu bọ lati ilu Shagamu, ilu Ibadan daru to fi jẹ wipe enia ti ọwọ ọlọpa tẹ le ni ogun, awọn ile ati Ṣọbu, Mọto ati awọn ohun alumọni ti awọn bajẹ le ni ẹgbaji pọun.

Awọn enia to njijadu lati gba ẹru wọn silẹ yinbọn to fi ara ba enia bi marun, wahala ni iwa janduku bayi nda silẹ nilu.

# Iku Oro Re Da? Alhaji Adelabu D'ologbe

ORO OLOTU

Agboju'gbanu ni irohin iku Alhaji Adegoke Adelabu ti o sele nipa jamba Moto l'ona Ipero si Ibadan nigbati Alhaji Adelabu npada lo sile lati Eko, iehinti o kuro nibi iwadi oro awon ilu kekeke.

TANI ADELABU

Alhaji Adegoke Adelabu ni Asiwaju (Leader) awon ljo Alatako ninu ile igbimo Asofin Ijoba Iwo-Orun, on ni Alaga igbimo ogunna - gbomgbo egbe Alakuko (N. C. N. C.) ni Ipinle Iwo - Orun. Alhaji Adelabu lo da egbe Mabolaje sile nilu Ibadan ti o papomo egbe Alakuko (N.C.N.C.). Ninu odun 1951 ni o dibo wo'le igbimo apapo nla ti ilu Eko (House of Representatives) o si di Alabojuto eto ilu ati ise alafia. (Minister of Natural resouces and Social Services).

Ninu odun 1954 ni Alhaji Adelabu dibo wo'le igbimo ibile ilu Ibadan titun ti nwon da sile, nwon si yan si ipo Alaga igbimo. Alhaji Adelabu ni nwon yan ni Akowe egbe titun ti nwon da sile ti a npe ni Yoruba Parapo, on si ni igbakeji Baba egbe Alakuko (N.C.N.C.) titi di osu November 1957. Alhaji Adegoke Adelabu lo si Meka ati Medina nigbati o npada bo lati Ilu Oyinbo ti nwon lo se apero iwe eto ilu Nigeria.

A bi Alhaji Adegoke Adelabu ninu odun 1915, o lo si ilewe giga ti Ibadan, Government College ati Higher College, Yaba, tilu Eko. O sise labe U.A.C. lodun 1936 di 1946, on si ni enia dudu ti o koko de'po Manager ti awon Oyinbo Onisowo U.A.C. ko ni eko. Alhaji Adegoke Adelabu te'ri gbaso nigbati o di omo odun metalelogoji laiye.

Ki Allah gbe si afefe rere.


## Lagos Executive Development Board

FREEHOLD HOUSES FOR SALE

ITIRE ROAD ESTATE

REEHOLD HOUSES (TWO, THREE, and FOUR ROOMS) are being built for sale. Price range: £1120-£1,670. The Nigeria Building Society will, if required, arrange mortgage loan terms for suitable applicants Prospective purchasers may inspect houses on site or the plans at 5 CUSTOM STREET, LAGOS where applications will be received.


## A Nfe Asoju

A nfe Asoju fun Iwe Irohin wa Eleti-Ofe lati gun awon Asoju wa ni awon ilu ti a daruko ni isale wonyi:-

Abeokuta. Ijebu-Ode, Ijebu-Igbo, Ile-Ife, Oshogbo, ati Port Harcourt.

E kowe si Olotu Iwe Irohin Eleti-Ofe Kosoko St, Lagos.

# Oba Obinrin Npale Ase Ojo Ibi Re Mo



Eniti o nwo ninu aworan yi ni Elizabeth Keji ti o nse oba obinrin ilu Gesi, lowuro ojo ti o se ase ojo ibi re ni odun tokoja. Ese gbogbo awon oluworan ti pe sinu Iga oba na lati wa fi oju woran iru ere ati iru ijo ti awon omo ogun oba yio se fun ti ase ojo ibi na.

Bakanna ni a gbo wipe oba obinrin na ti nse ipalemo fun ase ojo ibi re ti yio se ninu osu June 1958, lodunni, awon omo ogun si ti nwewe iru ere ti awon o se lati fi mu ase ojo na larinrin.

## Dokita Nimbe Se'daro Adelabu



Alhaji Dokita Ibiyinka Olorun'nimbe so wipe iku Alhaji Adelabu je adanu pataki fun iran Yoruba ati gbogbo Nigeria.

Alhaji Adegoke Adelabu je okan pataki ninu ogelu omo Yoruba to nja fun isokan ati om nira ile Nigeria labe apapo se ijoba, (Federal Government).


## HAPPINESS SUPREME!




"Ma gives me "BANWO" and so, I'm strong, robust and healthy"

DA EHIN-DIDUN RE DURO

nipa titete mojuto awon eree inu ati apo-ito re

LO

DeWitt's
Kidney & Bladder Pills



Ki o si bo lowo awon irora ti o nko e sinu arun

LAKUREGBE, ARA-RIRO, EHIN-DIDUN ati, Awon IYONU APO-ITO

DeWitt's
Kidney & Bladder Pills

L'arin wakati die ni wa a ti Ri ayorisi ise re (Ito a mu awo miran wa)

## Baba Oniwe Irohin



Ninu ose ti o koja lo yi ni alejo nla obinrin pataki kan ti o je oyinbo lati ile Israeli de si ilu Eko ti gbogbo awon oniwe Irohin ilu Eko poju sinu ile igbimo nla (House of Representatives) lati bere oro lowo oyinbo ajeji na. bawonyi:- Se ko sa ti akan ti a fi ri o nile Nigeria? Kini ohun pataki ti o wa se ati kini ise re? pelu iru awon ibere be be. Ogbeni E. S. Ikoli ti a owo yi, je ogbologbo ati asiwaju fun Oniwe Irohin ile wa nihin je okan ninu awon onirohin ti o lo ba alejo nla sa soro.

# Gbogbo Oro Ki Iye Lori Abahun

Lati Owo Sakiru A Olaiya

Emi Agbedegbeyo tun de, Itan mi na bere ni yi o. Tani o mo wipe ohun gbogbo kiye lori Alabahun ati Yanrinbo iyawo re.

Ki Olorun oba ma je ki enu wa se iku pa wa bi ti Ijapa, ti oju re ba ri ko si le dake. Enyin elegbe mi, e sora pelu oro siso.

ENU ABAHUN IJAPA SE IKU PA A

Ni ojo kan "Ijo kan ki tan laiye" Abahun Ijapa Tiroko oko Yannibo jeun o yo tan, o nrin kiri ninu igbo.

Ori igi obi kan, o si tun ri ori oku gbigbe kan ti won fi ha a lori mo ro pe ki awon ma ba ji obi na ka si.

Rin ti Alabahun ri afi enu gboro ti o ni ipin aise ipin airo ori oku gbigbe ori obi o ma ku ijoko". A fi bi ori oku gbigbe ti dahun "Oni iwo Alabahun enu re ni yio se iku pa o".

Ijapa gbera o di ile lodo Yannibo iyawo re o rohin fun awon mejeji si tele ara won o di idi obi ori oku gbigbe tun soro.

Ijapa gbera o di odo oba ilu orohin fun oba bi asa ile wa ki enia to le ba oba soro yio koko yi le na yio so wipe Kabiyesi oba alase ekeji orisa.

Ijapa ko o ro sugbon oba ti mo lepuro ko le gba oro re gbo nitori ti o ti mo Ijapa tele. Oni bi on ba tele Ijapa de ohun ti ori oku gbigbe ba soro on yio so Ijapa di Olowo sugbon bi ori oku ko ba soro on yio pase ki won pa Ijapa

Gbogbo ilu tele Ijapa' oba ati awon Ijoye pelu ilu ti adun lehin won bi eni pe won nse igbeyawo fun Ijapa, nigbati opolopo enia nri lori enia ti o mu oju gberee ti o si nbi oju titi bi ayan atijo.

Igbati Ijapa de ohun o ni "Ipin aise, ipin airo, ori oku gbigbe ori obi o ma ku ijoko" Ori oku gbigbe ko dahun, Ijapa tun soro, o kigbe nla, ori oku gbigbe ko dahun.

Igbehin, inu bi oba, o si pase ki won pa a bi Ijapa ti ku tan ni ori oku gbigbe soro ti o ti so, fun Alabahun pe enu re ni yio se iku pa o.

Gbogbo enia ba ke ha! O soro, o soro, o soro, Kinni o ye ki oba se fun Yannibo iyawo Ijapa ?.

Mo gbe t'ana danu, me gbe imiran de ! enyin okawe wa, e fi iye denu, oro nbe lenu mi bi Awoko, ogbon si nbe lori mi bi Atikekere sogbon.

Emi Agbedegbeyo nba yin soro ti yio fun yin ni ogbon ati oye. Itan ti mo so yi dori Kiniun ti o je ti o yo tan ti o nwa bekunbekun kiri, ti o si tun ni on fe mo bi wahala ti ri ti yio si ri saanani.

Nigbakan Kiniun ti o ti ni agbara ti o si nri onje ojo je lasikolasiko gbo ti awon elegbe re nsoro ti okan wipe on ti wa ninu wahala lati bi ojo meta ati pe ko si ohun ti o dabi wahala ninu aiye.

Kiniun ti ko mo wahala ninu ati wa wahala lo. Igbati Kiniun yi fe jade nínu ile re o wi fun iyawo re wipe on nwa wahala lo. Ibiti o ti nso eyi ode kan yo gbo Ode na si je eniti Olorun fun lebun ati ma gbo oro awon eiye ati eranko o si ti gbo ohun ti Kiniun so.

Ode mu ona pon o di ona ti kiniun yio gba wa wahala lo o pade Kiniun o si bere ohun ti o nwa lo; Kiniun ni wahala ni on nwa lo. Ode se ileri ati ba wa a sugbon o ni ki Kiniun pa eran fun on.

E ri omugo Kiniun ti o je ti o yo tan ti on wa bekunbekun gbaradi o si pa eran nla fun ode kitikiti Igbati o pa eran tan Ode ni ki o duro de on o si lo si oja lati lo ra opa wahala eyi ti o nje agogo.

(Wo yoku loju ewe kerin)

ELETI ỌFẸ
A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM

28, Kosoko Street, Lagos "ELETI - ỌFẸ LAGOS"

P. O. Box 467 Phone 23370

VOL. X, NO. 565, LAGOS, SATURDAY MARCH. 29. 1958

# Irohin Koto Afojuba

Owe awọn Yoruba oke wosika wa ọsẹ yi l'o jade lẹnu wa nigbati awọn Oluwadi ifoiya awọn ilu kekeke to mbẹ nilẹ Nigeria tun mu ipade ijoko sọrọ wọn wa silu Eko ni ọjọ Monday ọsẹ yi, lati gbọ paripari ọrọ ilu Ilọrin ati ilẹ Kabba wipe ki a pa wọn pọ mọ ilẹ Yoruba ti iṣe ọmọ-iya wọn.

Oloye Rotimi Williams ti iṣe Alabojuto ododo (Minister of Justice) fun ijọba Iwọ-Orun fọ'gi lọjọ na niwaju awọn oluwadi nipa afihan gedegbe to ṣe fun wọn wipe ayaṣebi a ba pa awọn enia ilẹ Ilọrin ati Kabba ti nwọn jẹ iran Yoruba pọmọ awọn ọmọ iya wọn ni ipinlẹ Iwọ-Orun ni ohun ti o le mu alafia ati irẹpọ ba ominira ilẹ Nigeria.

Ki ako t'awada kuro, Oloye Rotimi Williams to ra lẹgberun ọkẹ nibi asọye ọrọ, k'a ma ṣẹṣẹ tun sọ ti igilangọ ede oyinbo Gẹsi to ye koro lẹnu aromadahun oloye wa na.

Otitọ ni owe Yoruba to sọ wipe "Irohin koto afojuba" bi a ti ngbọ irohin wipe ogbogi ninu iṣẹ agbẹjọro (Lawyer) ni Oloye Rotimi Williams, ko si ani-ani nibẹ, bi enia si fi ẹgan kun didun ni a o ba ninu afara oyin.

## Imoran Fun Enyin Abiyamo

Enyin abiyamọ ẹ wa ra ỌMỌRELA o dara pupọ fun awọn ọmọde.

Ama jẹ ki omode ri orun sun daradara o dara fun otutu, iko ati orisirisi arun miran ti o ma mba ọmọde ja ni asiko ehin. Ọpọlọpọ abiyamọ lo ti lo egbogi yi fun ọmọ wọn ti wọn si sọ wipe o dara pupọ fun awọn ọmọde

ỌMỌRẸLA BABY MIXTURE
(Ṣile Meji Abọ 2/6d Fun Igo Kan)

O wa Lọdọ
COMMERCIAL MEDICINE STORES
(Qualified Chemists)
10, VICTORIA STREET, LAGOS.

## FA OGBON ATI IMO YO
## IDIJE TI YORUBA (EKETA)
## £200 Ni Fun Ebun Idije Yi

IPO EKINI £120; EKEJI £50; ẸKẸTA £20

£30 wa fun awọn miran ti o ba tun ṣe daradara

AKIYESI: Fi lẹta kan si ibi ti o ṣofo ninu awọn orukọ kọkan ti o wa ni isalẹ iwe yi. Lẹhin na ki o fi idahun rẹ sinu apo iwe pẹlu Postal Order 2s 6d (ṣile meji abọ) ki o si fi ranṣẹ (by post) si MANAGER, AFRICS NEWS AGENCY, PRIVATE MAIL BAG No. 5164, GENERAL POST OFFICE, IBADAN, NIGERIA. 1s. (ṣile kan) jẹ owo afikun orukọ ti ẹ ba rope o tun yẹ dipo awọn kan ti akọkọ. Ẹ o fi gbogbo wọn sinu apo iwe kanna. Ẹ le lo iwe miran dipo fọmu yi lati fi ṣe idahun idije yi.

| | IDAHUN | ITỌKASI IDAHUN |
|---|---|---|
| 1 | ALA—— | Ọba wo lo jẹ pataki julọ ni ilẹ Yoruba? |
| 2 | ——RINDIL—— | Ọba melo lo ni ilẹ Ekiti? |
| 3 | A——JỌBI | Eyi jẹ orukọ Yoruba |
| 4 | ———SAMI | Eyi jẹ orukọ Yoruba |
| 5 | ỌLỌ—— | Eyi jẹ orukọ kan ninu awọn ọba ilẹ Yoruba |
| 6 | A—A | Eyi jẹ orukọ ilu kan ni ilẹ Yoruba |
| 7 | ———MAWE | Orukọ ọba kan ni ilẹ Yoruba |
| 8 | MOLA—— | Orukọ Yoruba. |

Oruko ______________________

Address (Ibughe) ______________________

______________________

Iye owo ti mo fi ranṣẹ ______________________

Tete fi idahun rẹ ranṣẹ ki toto ọjọ Monde, 7th April, 1958. Esi idije yi yio jade ninu "IWE IROHIN YORUBA" ni ọjọ Mọnde, 14th April, 1958.

## Gbogbo Oro Ki Iye Lori Abahun

(O bẹrẹ loju ewe kẹta)

Oso agogo mọ ọrun Kiniun, bi awọn ẹlẹgbẹ rẹ bati gbọ agogo, wọn a bu si o di bo lọ o yago'mi, ebi pa Kiniun oju rẹ fẹrẹ yọ.

Igbati o tun pade ọde ti o wa wahala fun o fi ori balẹ o ni Ọlọrun fi enia ṣe ọga ẹranko. o ni ki ọde ba on tu agogo Ọde wa bi lere pe ṣe o ti ri wahala to? Kiniun ni bẹgan lori. Ọlọrun ma gbe ọpa wahala le wa lọwọ (Amin).

Ọde tu kuro o wa sọ fun pe ohun ti wọn npe ni wahala lori yen. Ni Kiniun ba ba ọna tirẹ lọ laifesi mọ.

Fa ọgbọn yọ, ere idaraya kekere yi ni mo fi si iwaju yin. Magbagbe pe ila kekere kan duro fun ọrọ kan.

1. Ẹranko bi Ekute --E--
2. Ọgede ti adin ninu epo --D- 3, Ọdun awọn Imale --E--
4. Onje ti owo pọ larin ilu Ekiti -Y-- 5, Baba eiye --O--- 6, Onje ti owo pọ larin ilu Ijebu --R- 7, Isu ti adin ninu epo -U--- 8, Afi nge nkan -B- 9, Ole bi igi, be a nje ninu ọbe -A---

### LEMỌMU AJAKUTA PADE ALUFA AJARAMỌKEWU

Olotu,

Jọwọ gba mi laye sinu iwe irohin rẹ lati kesi awọn Alufa agbaiye lati gba mi kuro lọdọ Alufa Onirọbi-robi kan ti mo ba pade ni ilu kan ti nwọn npe ni Okan.

Ọkan ninu awọn ọmọ kewu alufa yi nke tira Mọdiwu, o wipe "Alila yauja, bili mu asabi wa ansila" Alufa na tunmọ rẹ bayi pe :- Seyidina Aliiyu sọ pe; aiya on nja nitoripe on ko mọ eniti on yio fe ninu Asabi ati Wosila".

Bayi ni Alufa na tumọ kewu yi lọna ti o wu. Nje enyin Alufa agbaiye e ba wa fasara aya yi nitoripe nigbati mo tọ Alufa na s'oju ọna, nṣe lo mura tan lati na mi.

Emi ni
Lemọmu Ajakuta.

## Rogbodiyan Nro Dede Ni Oyo

Ọkọ-ilẹ meji (Motor-Lorry) ni awọn fiko awọn Ọlọpa wa si Ọyọ lati wa bojuto alafia ilu nipa ti ọrọ Oniwasu ninu Awẹ ti a ṣẹṣẹ bẹrẹ yi.

Rogbodiyan ọrọ na bẹrẹ lori wipe awọn kan fẹ yan Oniwasi miran dipo Alfa Shehu Busari ẹniti baba rẹ ti fi bi adọta ọdun ṣe Nọsia ninu Awẹ ni adugbo Pakoyi nilu Ọyọ, lẹhin iku baba na ọmọ rẹ Alfa Shehu si ti g'ori oye Wasi ẹiṣe na ti le ni ogun ọdun sẹhin ki awọn ijọ kan to fẹ yọ kuro lọdunni.

Gẹgẹbi a ti gbọ ni wipe awọn fẹ fi ọrọ iṣelu kun ọrọ na. Alufa Oniwasi na jẹ alatilẹhin fun ẹgbẹ Afẹnifẹre (A. G) ṣugbọn ẹnikeji jẹ Ọyọ Parapọ, alatilẹhin fun ẹgbẹ Alakuko (N.C.N.C.)

Awọn Ọlọpa koiti fowọkan enikan, nitoripe tọtun-tosi awọn koiti kọlu ara wọn.

## B. O. A. C. Yio Gbe OKo Titun Jade

Awọn Oyinbo ti nwọn npe ni B, O, A, C, ẹgbẹ Olẹkọ Ofurufu, fi ogidinlẹjẹ owo bi iwọn £60,000, 000, lelẹ Sọdo awọn Oyinbo ti o nṣe ẹda Okọ Ofurufu ti nwon npe ni Viekers Armstrong, ki nwọn fi kan iru Okọ Ofurufu kan ti nwọn npe ni V' C, 10 Ọkọ ofurufu marundilogoji (35) ni nwọn ma fi gbogbo owo na kan, ọkọ kọkan yio gba enia ti o pọ to ọgọfa enia, yio si lagbara lati ma rin ẹgbẹta busọ ni wakati kan.

Nigbati nwọn ba pari awọn ọkọ ofurufu na tan, nwọn o fi mẹwa ranṣẹ silẹ Afrika, mẹwa silẹ Australia ati mẹwa si agbegbe ilẹ Egypt Okọ nwọnyi yio bẹrẹ si iṣẹ ni ọdun 1963.

## Itan Oduduwa

**Orisa omo meji ni a gbo pe Oduduwa bi. Awon ti o bi siwaju ki o to joba ati awon tobi lori oye oba. Awon omo to bi ko to joba ni oba Accra, oba Ajase, oba Dahomi oba Igerefe ati opo ti a ko le ka tan.**



## Itan Ogun Eleduwe

**Ogun Ilorin ko wi fun ara Igbomina tele pe on mbo nitoripe nwon fe ko awon Igbomina ni eiye-ko-soka. Ewe, Awon Igbomina ko fi igbakan bora ogun sile, nwon le jagun, nwon si l'ogun, nwon ni esin nwon si ni enia. Awon ni nwon ma nki pe "Omo obe olojumeji", bi egbaa oke, omo kesinloro.**

1084

# Keep your engine "in tune!"






Gbo didun ise ero Moto re bi o ti nsise daradara. Epo Mobiloil l'o jeki o nsise be, ti gbogbo awon ero re fi nsise deedee pelu igbadun ati itelorun. Ko ni je baje, yio ni agbara, yio si le sare, emi ero Moto re yio gun siwaju. Bi o ba je epo Mobiloil ni o nlo, enikan ko ni gbawaju lowo re.

Mobil

MOBIL OIL NIGERIA LIMITED.

## Oba Alake Fi Igbagbo Re Han

Alaiyeluwa Sir Ladapo Ademola, oba Alake Abeokuta so wipe on ko gbekele ohunkohun kan ti o ju Olorun Baba Olodumare eniti o nse Alase aiye ati orun lo.

On gegebi Onigbagbo gba Jesu Kristi gbo ko si si enikan ti o le so wipe on ri emi Alake nibi isin Iborisa ri. Ninu ipo oba ti mo wa loni yi gegebi oba Alake ko si ile isin Olorun ti emi ko nlo. Bi o tile je wipe Sosi ti Ake ni Sosi Oba ilu Egba ko di mi lowo lati lo si Sosi miran.

Ko nse wipe boya nwon sese gba be ni o ti wa be latigba ti awon Egba ti fowo-sowopo nse ijoba.

Bakanna ni mo tun gbagbo pe Olorun Olodumare ni awon Imale isin lona tiwon mo si ma nlo ba won se esin ninu Mosalasi nigbakokan.

Nilu Abeokuta ni isin Igbagbo koko bere ki o to wa tan kale Nigeria, mo si gbagbo pe Imale ati Igbagbo ni yio jijo ma gbile mo ni igbolya lati so wipe siwaju ki Iselu to bere nile Yoruba, ni awon Egba ti nse ijoba ara won, ani paapa ki oyinbo to de. Ilu yi yio di alagbara kan larin ile awon enia dudu, awon odomode oni ni yio di baba orile-ede lehin ola.

## Kere o!

Ati ni orisirisi ogun German to sese de, fun oiruru aisan tokunrin obinrin. Tete wa ra tire k'o to tan.

**J. A. AJAO BROTHERS**

MEDICINE STORES

7, Egerton Road, Lagos.

# Idahun Si Ibere O.B

Odomokunrin kan ti o nje O.B. lo bere oro yi lowo mi wipe ese ti adie ti a mo ni Akuko ko tun le ko mo, ati ti abo adie fi nyo ogbe lori ?.

Gegebi oro ibere na ti ye mi si niyi wipe, ohun gbogbo ti enia ba nse ni lati je iwon-tun wonsi. Nigbati akuko adie ba nfi gba gbogbo ko bi akuko, si akoko bere kiko re ohun ko ni goke tobe. Sugbon nigbati o ba nfi gbogbo igba ko bi akuko ti ko simi kerekere ohun re yio ma goke to be bi o ba ko ni adugbo keta keteketе n i enia yio ma gbo ohun re.

Ohun gbogbo fe iwon tun wonsi nigbati akuko ko ba fi iwon tunwonsi-si kiko re daju daju ere ni lati de o si ni lati di Pawu.

Bakanna ni fun abo adie ti o nfi ojojumo tele akuko lehin nigbati akoko bade, yio yo ogbe lori, yio si ma yin obu nitoripe awon akuko ko ni mo o wipe abo nise nitori t i o yo ogbe lori. I d i oro m i niyi.

Emi ni
Lemomu Ajakuta

## E Ma Ka Iwe Irohin Eleti-Ofe Ki E Si Ma Polowo Oja Yin Sinu Re.

ERO ATATA TI NGUN IRESI T'O SI NFE MO TONITONI
(Ancomill)

Ero na rorun lati lo, o si nse ise kiakiabadun; o to gbe'kele, o yayi, ise re si bu-aiya.

Leselkese to ba ti da iresi emikunda si i ni yio gun u, ti yio fe e, ti yio si so o di funfun laulau.

A. G. LEVENTIS & CO Ltd
(Technical Dept.)
Ebute-Meta, Ibadan, Kano
Port Harcourt ati Aba ni e ti le ri ra.

# Asoje Oro

**Bi Olododo ba ns'ododo, Ododo Akitoye a ma sa ape sindodo ninu oro ododo re we awo lati ma fi je dodo itan l'oju awon omo re, nitori ki asododo le gbile larin awon omo Oba. Adeniji Apata Sinaba, bi o tile ti je omoba to ngbero lati joye Onisin silu Isin. Sugbon awon Isin ko gba a loba.**




The Western Region Government has set up two important special agencies for the promotion of development within the Region.

These agencies are the Western Region Production Development Board and the Western Region Finance Corporation.

The Board has undertaken the establishment of both large and small scale plantation schemes throughout the Region involving a capital commitment of approximately six and a half million pounds.

Both directly and in partnership with outside capital and technical interests, the Board is also engaging in various industrial activities including fruit canning, rubber processing and plastics manufacture. For future developments in both the agricultural and industrial fields, the policy of the Board is to seek technical partners and the maximum outside capital participation.

The main object of the Finance Corporation is to make available short and medium term credits at reasonable rates for approved applicants in both the agricultural and industrial fields.

Numerous local Loan Boards have been set up to facilitate the handling of small-scale agricultural loans.

Every encouragement is being given to community development effort.

A provision of £900,000 has been included in the Government's 1955-60 five-year plan for grants to communities which show practical readiness to help themselves.

*Issued by the Western Nigeria Information Services*

## Ote Ti Awon Eru Sango Di

Nigbati Gbonka ti wipe ese ni Oba Sango fe ki Timi pa won, gegebi o si ti je agba ati asiwaju larin awon eru Sango, o ba awon elegbe re soro pe ki awon se ifanisowo fun ou lati ba oba ja, gbogbo won si je ohun fun.

O si se lojo kan ti oba Sango wa ni apejo Oyomisi Gbonka lo ko bo siwaju o wipe enyin Oyomisi mo ti di Agbati lodo oba tobe ti ko le pa mi mo.

Itorina ilu yi ko le gba awe mejeji pa po; ayafi ki Oba filu silu tan on titi ojo meje loni. Bi o ti soro yi tan li o si pora awon olori ninu awon eru re bere si fi abuku kan Oba Sango, awon si ndi afeti bi awon ti nsoro na tan. Eyi ni ibere ote Oba Sango ki o to jade kuro li Oyo.

## Akiyesi Pataki

A fi eyi kede fun gbogbo enyin Asoju Iwe Irohin wa nile Yoruba. l'oke Oya, nile Ibo, l'oke Okun ati nilu Oyinbo wipe enikeni ti ko ba fi owo wa ranse ki osu to pari ao ko oruko re fun Loya Eleti-Ofe, ao ba se ejo ao si gba owo irin ese lowo re.

OLOTU.

## E FI OJU S'ONA



Ogbeni J. O. SHOYINKA

Aka gbadun itan l'orisirisi ylo bere si jade ninu Iwe Irohin wa yi ni ose to mbo, lati enu gege Ogbeni J. O Shoyinka "Aloyin-l'ohun bi Omoge Imaro".

Tete sanwo tire sile ki o ma ba sabamo.

## Report On Andrews Liver Salts

The individually packed doses of andrews Liver Salts were used to advantage during the expedition International Geophysical Year 1957 - 1958.

The refreshing drinks these salts made were appreciated by members at altitudes, where, according to the expedition's doctor, dehydration caused by a lack of sufficient intake of fluids has to be countered.

Only half of the standard Individually packed dose was required to make a very refreshing drink without too severe a laxative action. These packages were carried by members in their pockets at altitudes of between 10,000 and 16,000 ft and were used a great deal.

## Kosi Epo Nile Ikpe Ati Ossiomo

EKO. Koto ti awon oyinbo elepo moto ( Shell B.P.) gbe si ilu Ikpe ati Osiomo bi koto epo na ti jin to awon ko ri epo ninu re.

Koto ti awon gbe si ilu Ikpe ni Ile-Orun iye ese ti won gbe je 8,953, epo ti awon ri ko to okan rara.

Nibi koto ti Osiomo jijin re je 12,063, awon ko ri epo aladojo ninu re. Gbogbo ero ti awon fi ngbe ile ni awon o ko lo si Etiopia ni agbegbe Iwo-Orun lati lere si ile gbe ni osu ti o mbo.







With its deep broad tread, resilient carcass, super tough sidewalls, heavily strengthened buttresses and powerful beads, India Giant tyres give the finest road performance available today.

TAYA INDIA

Yi ni koko ti ki njeki ese oko ye loti ile o lagbara d'opin, on si ni Taya to l'asape julo lode t'oni. Ti le ri ra ni ode

LEVENTIS MOTORS

Private Mail Bag 1013, Ebute Metta, Phone 45011

IBADAN-KANO - ABA - PORT HARCOURT.



SEVEN ! SEVEN!! SEVEN!!!

**YORUBA COMPETITION No. 9**

**£200 Awaits You**

1st Prize £100: 2nd £50: 3rd £30 Consolation £20

Closing Date 14th April 1958 Results 21st April 1958.

HOW TO SOLVE: Fill the missing letters in the clues provided, post completed entries accompanied by Postal or Money Order to the MANAGER AFRICS NEW AGENCY, Private Mail Bag, No. 5164, General Post Office, Ibadan, Nigeria. 2s 6d for one entry and 1s for every additional entry. Plain paper entries accepted.

| | | |
|---|---|---|
| 1 | — — — — — W — | O je oselu nla kan ni Naijiria |
| 2 | — — ASA | Okunrin yi ti di ologbe l'EKO |
| 3 | I — — R — | O je ilu kan ni ile Yoruba |
| 4 | — — AN — I | On ni akobi omo Oduduwa |
| 5 | — L — FIN | Ilu nla kan ni ile Yoruba |
| 6 | — — — MAWE | Oba nla kan ni ile Yoruba |
| 7 | ORIMO — — — — | Eyi je Oruko ni ile Yoruba |

NAME ____________________

ADDRESS ____________________

____________________

P. O No ________ Value ________ No. of entries ____


Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company 28, Kosoko Street P.O. Box 647 Lagos Phone 23370